# ROGBODIYAN SELE LARIN OBA ADELE ATI KOSOKO




ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO




VOL. IX No. 550. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 14, 1957. KỌBỌ MEJI (2)

## Rogbodiyan Be Sile Larin Oba Adele Ati Oloye Kosoko

**EKO.** Rogbodiyan kan tun bẹ silẹ nisisiyi larin Alaiyeluwa ọba Adele ati ọkan ninu awọn Oloye rẹ Aminu Kosọkọ ti o nṣe Oloye Asajon, Ọlọja Ereko. Gbogbo awọn Oloye Onifila funfun lo wa lẹhin ọba, ti nwọn si fi ara mọ wipe, ki a rọ Oloye na l'oye nitori iwa afojudi ati girimọnkayi rẹ ti papọju.

Awọn ẹbi Oloye yi papa ni ki'lo ṣubu tẹ awọn "ẹniti a ti nwa lati sunjẹ, ti o fi ẹpo para tan ti o wa lọ joko sidi ina".

Awọn apakan sọ pe ki a yọ kuro lori oye, awọn apa keji ko gba bẹ. Ọrọ na si nfe bi Iṣe ati Adubi ni toripe awọn ẹbi Oloye na nfẹ da si meji lori ọrọ yi.

Ọpọ ninu awọn Sanmọri ilu Eko ni ko fi ara mọ tẹmbelekun awọnyi. Gbogbo ero wọn nipe, ki ilu Eko tutu pẹsẹ, ki ilu si



OBA ADELE TILU EKO



OLOYE AMINU KOSOKO ASAJON TI ILU EKO

roju-raye ki o maṣe si ogun tabi ọte mọ larin ọba ati ijoye re. Aṣa awọn Oloriṣa Egungun, awọn lo ma nkọrin bayi:

Ẹnyin ọmọ Ọjẹ Elegungun
Ẹnyin abilọjẹ o tun ojẹ ṣe:
Nitorina, ẹnyin ọmọ Onile, ẹtun ile ṣe o.

## Omo Oba Oyekan Di Alumogeri Silu Oyinbo

Irohin ti a ri gbo ni wipe Omo Oba Adeyinka Oyekan ti o mba Alaiyeluwa Oba Adeniji Adele Keji ta konrongbon lori oye oba ilu Eko, ti o ro'jo larin ilu Eko, ti ejo re ko ta, o tun ro ejo arotunro, ko moyan lori, o gbe ejo re losi Kotu Kotemilorun, o jebi.

Sibesibe, o tun wipe ejo na koiti te on lorun, o di Gbongan Oba (Privy Council) nilu Oyinbo nwon tun da le'bi, jagun wa taku wipe, ayafi bi nwon ba tun ejo na yewo, se enyin na mo wipe Ijoba Gesi ni suru pupo, nwon tun ejo re yewo, ko muro, o tun jebi.

ITIJU PAMI ARE EPE

Itiju ko jeki oloro le pada wa sile mo, o kuku satipo silu Oyinbo nisisiyi, a gbo wipe gbese owo ile ta haya ti se si lorun, Onile si ti ni ki o jade bi ko ba ri owo san.

Eyiti o ya wa lenu ni wipe Ogbeni Bensini ti o je alagbonrandun ati alatilehin fun omo oba Adeyinka Oyekan so wipe awon ko gbo nipa iponju owo ti o ndamu omo oba na nilu Oyinbo. Oro na wa fa waka awon imale yi wa i-

Goroso d'onibara

enit'Olorun ba bun ko bun-u,
Jimo koiti ku, koiti ku Ebi ti
paro s'aiye.

Imoran ti wa ni ki awon alatilehin re ro kan se zidi irohin ti a gbo yi.

## Awon Ole Ibadan Nwo Aso Bi Obinrin

**IBADAN.** Ni lọlọ yi ni a gbọ wipe awọn ọlọṣa pataki-pataki ti ilu agbegbe wa lati oriko lati agbegbe miran de ibomiran ni wọn wa nṣe iṣe ọlọṣa ni ilu Ibadan. Ni ijọta ni a gbọ wipe awọn kan di ilẹkẹ bebe, wọn fi yẹri si eti, wọn fi owu si eti wọn si tun ro aṣọ igba si idi. Ṣamọ-ṣamọ, a jẹ ọkunrin ni wọn Igbadi ni ilẹkẹ wọn.

Ni agbe-gbe kan ti a npe ni Eko-tẹdo ni Ayiluka Eleti - Ọfẹ gbọ wipe wọn wọ si. Wọn pọ pupọ, wọn si ti pin ara wọn kakiri - omiran ni Isalẹ-Alafa, opolopo ni Oke Padi, Oke Foko, Aminigun Idikan, Gbagi, Alafara ati awọn agbegbe bẹ bẹ:

Ni lọlọyi ni a gbọ wipe awọn diẹ ninu wọn bẹrẹ iṣẹ wọn lati wa owo lati fi ṣe ọdun. Ko nṣe wipe wọn jẹ Onigbagbo ta'i Imale.

Ayiluka Eleti–Ọfẹ ni on papa ko le sọ pato ti wọn nṣe.

Ikan ninu awọn ọmọ Ibadan ni opolopo ni o nfẹ ba awọn ni oriko jẹ. Ko nṣe wipe ilu Ibadan nikan ni awọn ọlọṣa gbe wa.

Eleti - Ọfẹ ni awọn ti gbọ nisisiyi wipe awọn ọtẹlẹmuyẹ (Ọlọpa) ti da kakiri ilu lati ma tọ pasẹ wa idi iṣẹ buruku awọn Ọlọṣa yi.

## Orin Ti O Nsaju Ote

Olotu,

Inu mi yio dun bi enyin ba le fun mi ni aye die ninu iwe yin osose lati te iwe mi yi. Emi ko nse omo ile Yoruba, sugbon ni ati kekere ni mo ti de ile Yoruba mo si lo si ile iwe nibe. Iyen na ni o je ki nmo iwe Yoruba ka die.

Ni ose ti o lo yi, emi ati iyawo mi ko fi idi redio sile lati gbo nkan ti won nse ni Ibadan nipa ere ajoyo ti ominira ti won gbe. Emi ko fe ki a puro mo gbadun orin opolopo ti won ko fun ajoyo ominira yi.

Eyi ti mo tile nko nigba gbogbo ati iyawo mi ni eyiti awon omo ilewe ko ni Ibadan ti enyin Eleti-Ofe te sinu iwe yin ni ose ti o koja.

Kilose ti awon Yoruba fi feran lati ko orin bi inu ba nbi won, bi won ba nba ore won ja ati bi won ba nba enia yan-odi.

Awa na ma nko orin asiko sugbon tiwa yato. Boya mo le ri eniti o le la mi loye oro yi. Iyen nipe orin lo nsaju ote nibi gbogbo?

Olotu,
emi ni tire,
C. Okereke
Ebute - Metta

## Obinrin Nilati L'oko Tulasi

TOKIO- Ijoba ilu Jepani ti gbe ofin kan jade wipe lati osu to mbo gbogbo awon wundia, Olomoge ilu Jepani, ti o to oko ni, ti ko ni oko, ti o nse agbere kiri ni lati loko pelu tulasi. Awon Oselu Japani so wipe gbogbo awon omoge ti awon ti fun ni iwe ase lati ma se ise yi, ni awon yio fa iwe ase won ya lati ibere odun ti o mbo.

Ayiluka Elet-Ofe ni on gbo wipe awon omoge ti o nse ise karuwa yi ni ilu Jepani nlo bi adota Oke ona meji (2,000,000). Opolopo won ni o nfi ise ile-ero tabi a nse ise "danasungbo bo oju lati ma se ise okunkun yi.

Ko nse awon omoge-ko loko nikan nilu yi ni jamba yi fe ba nitoripe a ti se ikilo wipe lehin osu Keresimesi adota oke o ona mokanla (11,000000) awon osise ilu yi ni ao da sile nitoripe ise ko si mo. Ni osu ti o koja yi awon konise ti ijoba mbo je adota oke ole oke mokanlelogun ati edegbajo, (1,835,000) nla.

## Irin Ajo Mi Si Ilu Iyanu

Lati owo Adex, Wonderful Ibadan

Ki nto le so oro kokan rara mo dupe lowo Olotu iwe irohin Eleti-Ofe mo si tun dupe lowo awon ti o ran mi lo silu iyanu na. Awon enibi Ogbeni J. O. Alebiowu ati Brother Babajide ati awon bebe pelu ti o si je wipe aye kosi lati le daruko won tan.

Enyin ara mi nipati Oluwa ki e ma reti oro ENMO mi na ti mo ri ni ilu Iyanu l'ose ti o mbo.

Bonbo Ri Gidi! bi ile ba da Omo Adete arin ayan

## Igbimo Ibile Ilorin Le Oloye Meji Kuro Nilu

ILORIN. Igb'mo ibile Ilorin, ninu ipade ti awon se ni agbala Oba Ilorin ni ojo Satide pase ki a le oloye meji kuro nilu won, ki a fi elomiran ropo won titi di ipari osu March odun ti o mbo.

Ohun to fa eyi wa ni eredi ilwadi ede aiyede to wa nilu won. Ni asiko ti a di won duro Babasale Ilorin Malam Aliyu ni yio ma se olori ti Afon, ati Magaji Moyaki ni yio ma se Olori Paiye.

Oba Ilorin tako ipinnu won yi, wipe on ko faramo ki a le awon Oloye na kuro nilu tabi ki a da won duro.

## Oloye Okorodudu Tajo De



OLOYE M. E. R. OKORODUDU

Awon ti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Okorodudu ti ise Asoju Ijoba Iwo-Orun nilu Oyinbo pelu Iyawo ati awon omo re, nigbati nwon gunle silu Eko ni ojo Alaruba (Wednesday) ti nse ojo kokanla osu yi.

Oloye Okorodudu so fun awon Oniwe Irohin wipe nigbati agere ise ti on lo se nilu Oyinbo lati odun keta sehin ti duro sinsin, eto ni ki on pada wa sile. O tun so wipe on ni ireti lati lo bere ise Agbejoro ti on ko (Lawyer) lehinti on ba ti sinmi die. On ko si so pe on yio tun jijadu ise ilu.

## Ise Iyanu Leyi

Omobinrin wundia kan ti o nse iranse tabi omo odo lo loyun fun oko, olowo na si gba oyun yi pe, ti on ni.

Lojo kan nigbati olowo yi ko si nile ti oko olowo re lo si bi ise iranse yi ro bi, o si bimo sugbon omo na ko kegbe iranse na se bi oku omo ni on bi o si lo bo omo na mole.

Ni irole nigbati olowo ati oko re de o rohin fun won bi on tise bi omo na ni oku Oko Olowo kebosi, o sare lo rohin fun awon olopa nwon si lo hu oku omo na jade si iyalenu won nigbati awon ri pe omo na si nmi ohunkohun ko si se omo na titi di isisiyi e o rise oba as'oku-di aye.

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Asoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo wa ranse ki osu to pari ao ko oruko re fun Loya Eleti-Ofe, ao ba se ejo ao si gba owo irin ese lowo re.

OLOTU.

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 6/- postage stamps by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England




## OLOGEDE



Okuta nla sele gbarago o nile o mu teremu teremu,

Mole Ajilu Mole Malaki Koroji, koroji Koroji

Eyo ti ko ba gbawa, Ko gbodo dagodo

D'agodo awa de'ga.

Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS

Read this list of popular titles



HMV YELLOW & RED DOG.

J2 6098 - Kelegbe Megbe/Odun Titun Owo Titun
,, 6099 - Agba Olorin/Busura Baba Osa
,, 6100 - Yawa Yesu/Omolere Aiye
Jimo Ojindo
&
his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM :-
1. Y. A. Bilesanmi - 87, Victoria St. Lagos
2. Animawun Stores - 24 ,, ,, ,,
3. Salawn Aremu - 73 ,, ,, ,,

HMV BLUE DOG
J2A 100 - Shogbola/Oluwa Gbawa Lowo Iku Ojiji
,, 101 - Bakare Alake/Ejire Baba Taju
,, 102 - Raimi Oga Ota/Wahabi Baba Fasila
S. Aka & his (Sakara) Band

OBTAINABLE FROM :-
Omobori-Owo Stores,
Lagos, Abeokuta.

Sold by all the best stores




"HIS MASTER'S VOICE" Yellow Label RECORDS

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# E L E T I Q F E

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 550, LAGOS, SATURDAY DEC. 14, 1957


## J. K. Randle, Orun 're

Ęniti o ba şe rere, ari ire, ęniti o ba şe ika, ari 'ka. Ęnirere ko ni ku sipo ika, eyi ni afi jẹ omitoro ọrọ wosika wa ọsẹ yi.

Gẹgẹbi owe awọn Yoruba, "Ọpa agbele'ka t'ẹhin l'oju". Ę jẹki ama hu iwa rere nitoripe iwa rere ni ẹsọ enia. Bi o ba di ọjọ kẹtadinlogun oşu yi titi di ọjọ kejidilogbọn. (17–28 Dec. 1957), ni ao ti bẹrẹ isinku ologbe Oloye Joseph Kosoniolu Randle ọ k a n ninu sanmọri ọmọ ilu Eko ti ofi aiye silẹ ninu ọdun tokoja lẹhin igbati o pada de lati ilu Melborne, ologbe yi loşe olutọsọna awọn ọ m ọ ilẹ Nigeria lọ silu Melborne fun ere idaraya, ti o si gba'yi to gbẹ'yẹ bọ wa silẹ wa, şugbọn nigbati o gba iyi na de ọlọjọ mu lọ.

"Adagba aini adie i r a n a, bi a ba ku l'ọmọde mẹsọ-mẹyẹ ni yẹni" eleyi jẹ owe awọn baba wa.

Bi aiye ba yẹni, k'amọ wipe ọrun ayẹni. Ao bẹrẹ isinku ologbe yi jakejado ilẹ Niger'a ninu oşu yi, ati ọmọde ati agba ati okunrin ati obinrin ati onile ati alejo ni yio ni ọwọ ni ẹsẹ ninu isinku yi.

Bi awọn ẹbi ati ọgba ologbe yi ti ngbe igba bẹni awọn Oyinbo alawọ funfun papa ngbe ẹsẹ lati şe aşeyẹ iranti Ologbe Oloye Joseph K. Randle yi. Ao şe Ęyọ Adamu-Orişa fun ikasẹ Oloye yi. Ęgbẹ Island Club yio şe gudugudu meje ni ọjọ na.

Awọn Awo ni sinku Awo, bẹni awọn Ọgberi ama sinku Ọgbẹri, Awo lo lọ leni o, Awo, J. K. Randle Awo ni.

## A NFE ASOJU

A nfẹ Aşoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ lati fi kun awọn Aşoju wa ni awọn ilu ti a daruko ni isalẹ wonyi:-

Abẹokuta, Ijẹbu-Ode, Ijẹbu-Igbo, Ile-Ifẹ, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kọwe si Olootu Iwe Irohin Eleti Ọfẹ, 28, Kosọkọ St, Lagos.





## Ogun Aran (Ejo Inu)

Aradan Worm Expeller jẹ ogun aran pataki fun ọmọde ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buburu ti o nba ọ ja ninu danu. Bi o ti npa aran, bẹni o npa ẹyin wọn. Wa ra tirẹ ki o to tan. Igo kan jẹ 2/6d. Owo-Ọkọ si jẹ 1/-.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.


## Itan Otito

Lati ọwọ Ęsọ

Ọkan ninu awọn odu Ifa Ejiogbe lo pa itan yi itan na si şọwọn gidigidi, lẹnu Babalawo agbalagba kan ni mo ti gbọ nilẹ Yoruba, oruko rẹ a si ma jẹ agbefala. Gẹgẹbi oruko Babalawo na, iṣẹ Awo lo şe titi o fi kọle, ti o ka'nsẹ, ọmọ mẹrindinlogun lo bi, şugbọn ko fun mi laye lati şe apejuwe rẹ de ibiti awọn enia le fi mọ ọ.

Tabi şe on na ni, o jare, Odu Ifa na sọ wipe Eke ti de ile aiye ti pẹ, on lo fi ẹtan kọ awọn ara ile I f ẹ wipe, ẹnikẹni ti igbesi aiye rẹ ko ba sunwọn, ki o pada lọ si ọrun lati tun yan, gẹkẹbi awọn Irunmọlẹ ti ma nlọ ti nwọn si mbọ. Okun ẹwọn t i awọn Irunmọlẹ awọnyi fi atakun lọ si ọrun na, mbẹ lọdọ Ajalọrun ni Ijebu Ife titi di oni.

Şugbọn nigbati awọn enia ko le takun gẹgẹbi awọn Irumọle, Eke lo fi ọna ọrun han awọn ara Ife. Akọbi ọmọ ti Oduduwa b i nje Abudu ọmọ re keji lo nje Otito.

Otito je Ọkunrin, o si je ọde ati alagbara. Awọn elomiran npe Otitọ ni Ododo, on kanna lo nje be. Eke ti lọ kere nile aiye ki otitọ to de. Otitọ a ma fi ye awọn enia wipe, Ife ni Odumare fe ju, enikeni ti o ba si nife, yio şegun awọn eleke, Ọlọrun yio si ma feran re.

Nigbati awọn enia ri wipe ohun ti Otitọ nsọ fun wọn dara, awọn bere si huwa Otitọ awọn si ngbadun aiye wọn. Otitọ kọ wọn lati ma bọwọ fun agba, o nkọ awọn enia ni Aiyajọ tabi Ọfọ lati ma şişe rere, lati ma fi tọrọ nkan lọwọ awọn Irunmọle ati lọdọ Odumare o tun fi kọ awọn ara Ife wipe ki nwọn to şe ohun-kohun ki nwọn ma ronu wo, bawo ni igbehin ohun na yio ti ri, nipa eko re yi, o ti ibe gba ọta lati ọdọ awọn ọmọlehin Eke, ti nwọn je arije ninu idaru şugbọn ealkan kole şe e nibi nişoju Oduduwa.

Nigbati Odudua pehinda Otitọ şe atilehin fun Abudu egbọn re şugbọn awọn ara Ife ko fe. Otitọ ati Abudu m ọ b e şugbọn Abudu taku pe on yio je oye oba na ati nipa iranlowo

(Wo yoku loju ewe keje)

## Nwon Ko Oro Oluwadi



ỌGBẸNI FATAYI WILLIAMS

Ęniti a nwo yi ni Ọgbẹni Fatayi Williams ti o nşe igbakeji Commissioner ti o ntun ofin şe, o si jẹ ọkan ninu awọn enia ti o binu jade ninu ipade igbimọ iwadi awọn ilu kekeke n i l ẹ Benin. On pẹlu Oloye Rotimi Williams ti o nşe alabojuto ododo nipa ofin nilẹ Iwọ-Orun.

# Olobi Titun Je Si Ilu Ilobi

ILARO. Ni aipe yi ni a gbo wipe Gomina Ijoba Iwo-Orun ti fi owo si oro a nfani-joba a ko fini joba ti Oba Olobi ni ilu Ilobi ni agbegbe Ilaro. Nigbati awon igbimo ocolu Egbado ro oro na lọ siwaju si ẹhin, wọn ni awọn fipe gbogbo ara ilu lo fẹ lati yan Ọgbẹni M. O. Ogunbiyi ni Ọba Ilobi dipo Ọgbẹni T. O. Adebọwale ti wọn sọ wipe awọn ko fẹ lori oye mọ.

Ayiluka Eleti-Ọfẹ gbọ wipe a ko aipẹ ki a to ja ewe oye le Olobi titun yi lori. Oye na a mọ ori o.

## AKIYESI

### Fun Awọn Ọkawe Wa

Afi eyi kede fun ẹnyin ọkawe wa wipe a ti fi aye silẹ ninu Iwe Irohin wa yi fun awọn irohin Igbeyawo, Ikomọ-jade Isinku ati awọn irohin ariya bẹbẹ.

E mu awọn irohin ayin wa fun wa, ao si ba yin tẹ jade.

Olotu.


**Kere o!**

A ti ni oriṣiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tokun ... tobinrin. Yoto wa ra tiri, k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos.


# E ma Ka Iwe Irohin Eleti Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re




**OVALTINE ni Elere idaraya nmu**

Nitoripe Ovaltine nfun ni ni agbara ti oduro O si nfun ni ni iṣegun. Ere idaraya a ma gba gbogbo okun inu ara lopọlọpọ - Ovaltine a si ma fun ni ni aiṣebo ara titun werewere ati agbara pẹlu okun.

Ogbon ọrọ ni a fi ṣe e lati inu awọn ayin, eso kruginn, wara, ti a si fi okan ele imerale pẹlu rẹ. Ovaltine gbadun ni mimu o si jẹ onjẹ to ṣaramu pupọ, gbogbo awọn elere idaraya lo nmu nibikibi. Fi Ovaltine ṣe ohun ipanu iọsan ati alẹ ki o to lọ sun.

Ovaltine [illegible] ọdun 1932 [illegible] Olimpik. Awọn elere idaraya ti Olimpik [illegible] Ovaltine [illegible]



**OVALTINE**

wa fun agbara at okun

# Alapara Ibadan Nki Yin o

OKE FOKO
IBADAN.

Ẹ wa wọmọ ọba to wa bẹ wa wo. Ominira tide lẹ yi o. Kabọ, mọ 'lẹ, a ki yin pupọ s'ajọyọ yi o. Awa niẹ orin ominira kọ niyẹn? A ni bi mo ba sun mo nfi ọrọ ominira yi la ala. Mo fẹran ominira pupọ. Ọmọ ominira ni mi.

Awọn kan tun kọ orin kan ni Oke Oluokun bayi "akukọ gagara to n'ẹ loke yi. Mẹsi ni o lo lọ. Ọpẹ lo ni Wẹsi akukọ lo ni Mẹsi". Orin lo nṣaju ọrẹ-ṣugbọn ọtẹ ti tan nihin ominira lo ku. Iṣẹ a wa owo a wa iyawo a pọ rẹpẹtẹ.

## IYAWO APAPANDODO

Awọn kanian-kanjan ni obinrin pọ ju awọn ọkunrin lọ ni ode Isẹnyin-bẹni ko nṣe oraye emi Alapara na ka awọn obinrin lọna ọja Gẹgẹ lana. Bi mo ba pade ọkunrin kan ma ti pade obinrin meje lọna. Eyi mu mi niran ofin titun ti awọn igbimọ Ilọrin ṣẹṣẹ mu jade wipe ki awọn ọmọge to ti to ọkọ ni ati awọn ile-mosu tete lọ ni ọkọ ki awọn mọ ba le wọn kuro ni ilu.

Mo gbọ wipe awọn ara ilu Jepani papa ti gbe ogun ti awọn "Karuwa" ilu wọn ti o pọ bi iyọ. Nibọ ni wọn da si?. Lẹhin ọdun emi na a fẹ ninu awọn iyawo apapandodo wọnyi owo ọbẹ lo ṣoro.

## ILE-ẸKỌ GIGA DA?

Awọn ọmọ ilewe ẹkọ giga ti ilu Ibadan ti ẹ npe ni (University College) Yunifasiti Kolẹji da? Wọn ni ẹkọ akọju ni o ba elewura lori jẹ. Ominira ti awọn ọmọ ilewe giga nfe ko ye mi si. Aigbọran ni eleyi ni tabi inira? Jesu ọkọ ope, jọwọ ma je ki nri awọn alakoba ti mo ba tun alọ si ilewe giga o. Ile e giga nikan kọ ati ilewe keke e ati ilekewu.

Aburo mi ti o wa ninu awọn ti wọn le awe mo ti ba kọwe e'e. Ma tun fi idọbale kun. Boya a tun le gba pada.

........................

# Ija Imale Ilu Oro Nfe Atunse

Jọwọ gba mi laiye lati fi iwe mi yi ke si gbogbo musulumi ododo, lati dide lati pari edeaiyede ti o wa ni arin awọn imale ẹkun mẹsan Oro.

Ọrọ na jẹ oniyalẹnu fun mi pupọ nigbati morika ninu iwe Irohin Imọlẹ ti 30/10/57. Eyiti Alufa Ọlọrunkẹmi, kọ jade nipa ọrọ na.

Nigbati mo ka ọrọ yi wo, o je oniyalẹnu fun mi pe ilu Oro ni iru edeaiyede bayi tiẹẹlẹ, ni mo ba lọ ri ẹnikan ninu ọmọ Oro, ni o wa ṣe alaye ọrọ na fun mi pe otitọ ni ija wa larin Imale.

Mo wa fi iwe mi yi kesi ẹnyin ọmọ iya mi musulumi ilu Oro, pe mo fẹ ki ẹ pe ara nyin ki ẹ pari edeaiyede na larin ara yin, ati papa ki ẹ pa irun Jimọh ati irun odun pọ. N'tori Ọlọrun Ọba, ati kiẹ ranti pe iru iwa bayi ko dara lati ma ki irun ni ọna mẹta larin ilu kanna.

Motun fi iwe yi kesi gbogbo ẹnyin Alufa ati ẹnyin Alahaji, ki ẹ dide si ọrọ yi ki ẹ pari ọrọ na, motun fi iwe yi kesi Alufa Ekemọde ati Hadji Animọshaiwun, Hadji Shaki, Alufa Oshishi, ki ẹ pe awọn janmọ ilu Oro ki ẹ ba wọn sọrọ, ki ẹ maṣe jẹki ẹsin Anabi Muhamed ba lẹ. Gbogbo ẹnyin Imamu ilu Eko, ati awọn janmọ ilu Oro ba nki irun ni Mọsalaṣi yin, ki ẹ pe wọn ki ẹ si fi ọrọ Ọlọrun ṣe apejuwe fun wọn.

Motun fi iwe yi kesi Ọba Oloro ati awọn Ijoye re, pe ọrọ yi ki ṣe ohun ti wọn ni lati fi dake rara, atipe ki Ọlọrun maṣe ba ilu Oro je mọyin lori. Ntoripe ilu ti wọn bati nki irun lọna meji, Ọlọrun a saba ma binu si iru ilu be ati papa Ọlọrun sọ ninu Alukurani pe e ko gbọdọ ki irun Ururba lọna meji, iyen ni irun Jimọ ati irun ọdun.

Ati papa ti eyin Ọba ati igbimọ ko ba da agunla si ọrọ yi ko ni ribe atipe ki e maṣe lerope ṣọgi o pọ

(Wo yoku loju ewe keje)

# Eyo Adimu



Ẹyọ ti a nwo ninu aworan yi ni ọkan ninu awọn Ẹyọ Adimu. Nṣe lo ti nfi Ọpabata rẹ te ilẹ ri, ṣugbọn nigbati Iga Ẹyọ (Captain) ki gbe Agan bayi wipe:-

Ija ranyin o-o-o-ro-o

Gbogbo awọn Ẹyọ yoku suraki lese kanna awọn si ọpabata wọn mọri gegebi Ẹyọ yi ti ṣe awọn si daro pada si Iga Ẹyọ na wipe Ogunye!.

A ṣaba-tibi awọn o si dahun pe Atib'-taba Itumọ Aro yi ni wipe Ẹnyin Ẹyọ Adimu ija kan fe be sile nisisiyi ẹ ti mura tabi e koiti mura awọn Ẹyọ yio si dahun pe awọn ti mura.

## ARO TABI ASỌJẸ TI A MA NGBỌ LẸNU ẸYỌ

Nigbati ẹnikan ba na ọwọ owo si Ẹyọ kan, iyẹn ni pe, o nfẹ dan Ẹyọ na wo bi o ba mọ awo.

ohun ti Ẹyọ na yio ṣe ni pe, yio kunlẹ, yio fi ikori ọpabata re te ẹni na ni atẹlẹwọ, yio si ma wi bayi pe :-

E yi Ato, E yi Agbọ, E yi Amọlọwọ, E yi A mọlẹṣẹ, E yi Afaiku ṣe baba wa, E yi A mọtimọ timọ, Hu-u-haha We ma jagiẹn diẹ. Ẹyọ na yio dide yio rora fi ọpabata le enia na.

## ARO TABI ASỌJẸ

Alẹlẹ we ma lẹ ọkunrin ma kue birimo birimo
Eniti ko mọ iṣẹ okunkun, Ko ma da oṣupa loro Hu-u haha.
Awo lo nsinku Awo, Ọgberi n si ma siaku ẹgberi
Emi Ayọnpọntan bi ẹni yan ede, Nimọdẹ Iraye Hu-u haha.

## Itan Otito

(O bere loju ewe karun)

Otito o joye oba Ife sugbon nigbati o di osu kata o wa'ja.

Sango ati Oranyan fi okan ki Otito wipe ki nwon fi joye oba na ki oye baba won mase pare, Otito si gba fun won be ni won ba fi otito joba Ife. Odu na so pe Otito lo odun meta lori oye ki o to ku, ati wipe jamba ni nwon se fun.

Nwon fi Otito sun esun wipe, ko jeki nwon enia sin awon irunmole mo, o ni ki nwon ma sin on, iru iwa yi bi Oranyan ati Sango ninu, t-be ti nwon ko ehin si; bayi ni Otito ba ku, sugbon lati igba na wa, bi enikan ba nse rere, nwon o wipe o nse otito.

## Ija Imale Ilu Oro Nfe Atunse

(O bere loju ewe kefa)

ni arin ilu ni e mawa fi oju re wo ti awon imale oro yi yato pupo si arawon ki e si tun wadi wo lodo awon Alufa ti o ni mimo dada. Nitorina ti esin Imale bale baje enyin ni Olorun yio ba ro ejo. Nitoripe enyin ni Olorun fi se olori si ilu Oro ati papa owe enyin agba tun so bayi pe "Agbalagba ki wa ni oja ki orun omo tuntun wo". Nitorina ki e mura dada ki e pari oro yi fun awon imale ti e ko ba feki olorun ba yin ro ejo.

Lehinna, motun fi iwe yi kesi enyin Alufa, ati enyin Imamu ati Janmo ilu Oro ki e pe ara yin kie pari edekoyede yi pelu ara yin, Nitoripe "kosi eniti oniki eje, kie to wa sope eyo" won ko fe ki esin Anobi wa laiye, sugbon Oluwa ni o ngbe esin ara-E ga, Nitorina, mofi Olorun oba be yin mofi Anobi Muhamed be yin Olorun yio tun ile ati ona yin se. Olorun koni so oko ibanuje si ilu oro, osi aja Olorun ni Olorun koni fi ba wa je.

Ki enyin gan na fi oju ara yin wo e ripe kosi ilu ti won ti nki irun Uduba lona meji ayafi ilu Eko nikan, ti be agidi lofa ti ilu Eko, ti enyin na na bau fi oju inu wo dara e mope akan se ni ilu eko gan. Sugbon ki be Olorun ma gba ile ati ona yin mo yin lowo.

Mo wa dupe lowo Ajijola Anobi, ati Alupha Olorunkeni ati Y. Ade Buraimoh ti won ti ko oro yi si inu iwe irohin abo fun gbogbo araiye, ki Olorun fi alubarika si ise yin o.

Abo mi re o, Oletu, Olorun yio fi alubarika si ise yin, e koni sile e koni simu, Oko oba koni sayin lese, Ami.

Emi ni,
Alufa Durosinmi






Awon gbajumo enia gba wipe gegebi mo ti je oga Ako-ile, mo mo nkan ti awon enia fe, mo si le so wipe Oti Star ni enikeni feran ju.

O da mi loju, ko si eniti o le m'oju kure ninu adun Oti Star; o dara to be ge, o si lagbara pelu. Tabi iwo yio tun fe si i ?.

# STAR



OTI STAR

l'o je eyiti odara ju! Beni Sammy Sparkle wi.



Awon ohun ... julo ni afise, Eso o ka barley to l'orun daradara ni a fi se Oti Star. awon enia ti o loye lori pupo l'o nsise Oti Star, omo, o si ni awo ... yayi.

Oti Star npa orungbe; adun re ko si iru re

## Igbehin Osupa Ti Rosia Gbe Jade

LONDON. Opolopo ni awon ti o ti mbere wipe Osupa ti awon Rosia ko. Ko gbe soju orun, nibo lo wa?

Iroyin ti a ri gbo lati ilu London ni wipe, ieho ti osupa na ti rin opolopo ibuso larin ofurufu, ara ti mu,o si ti ja lule sibi kan.

Ogbeni Fred Whipple ti o nse ara Amerika Olori awon aworawo to je wipe bi abere ba wa loju sanma yio ri, so wipe, gbogbo irinkerindo osupa na ni on ti nso lati igbati o ti jade, sugbon lati agogo meta owuru ojo keji osu December, ni on ti wa ti loju sanma.

Olori awon aworawo nilu Geri, so wipe on ko le so bi atubotan osupa na ti ri, nitoripe, on ko tun ri loju orun mo bi o tile je pe o si mbe yio ti fori kangbo pelu irawo miran.

Awon aworawo ti o mbe ni agbegbe South Afrika so wipe awon se akiyesi ohun kan ti o ja wa sile lati oju orun wa ti o si pon bi eje-ina, awon si tun ri ohun kan ti o dudu bi edu ti o tun ja wa sile pelu.

Nilu Jamani, awon aworawo ilu na so wipe, lojo keji osu Dec, 1957 Awon se akiyesi ohun kan ti o [illegible] ti o jibo [illegible] ojoro [illegible] olopa ti o ri [illegible] eyi le je agbotan osupa Rosia.

Okunrin kan ti o nje Joachim ti okan na ja lule si oko re, so wipe, okan ti o jona na dabi irin Aluminium.

Nigbati awon olopa lo se iwadi nkan na, awon ri pe, gbogbo awon ohun elo ti a fi nse Rokcti lo peju sibe. Eyi si ni atubotan osupa ti Rosia gbe si oju orun.

## Oga Ni Doherty L'aye-k'aye

Ni aiye ijoun, nigba aiye Doherty a gbo wipe ninu awon sawawu olowo egbe re nigbana, ko si eniti o lowo ti ale fi we Doherty.

Ko si olowo keqebi ti Doherty, bi o si ti lowo to, beni inu rere re po to, a ma se anu fun opo awon enia, nipa rirán omo won lo fun ilosiwaju ninu eko, o ni obinrin pupo bakanna lo si bimo pupo. Sugbon akobi omo re ni ogbeni Adebayo Doherty.

On ni Bigbaji Olorin fi korin bayi nilu Eko wipe:-

Ahon pelenu nje, Ejek'a mi, alaroye ode Josiah pelu Wusa pelu wusa o ore ni won lat'orun

(Iyoku Di Ose Tombo)

No. 181

# Public Notice

## Minorities Commission - Programme Of Sittings In Lagos

As already announced the Minorities Commission will hold sittings in Lagos after the sittings at Benin and Warri have been completed. The sittings at Lagos will be as follows :-

| | | |
|---|---|---|
| LAGOS | Sittings at | Commission's Offices |
| December 27th | The Committee Room, House of Representatives | The Governor-General Office and Council of Ministers. |
| December 28th | " | " |
| December 30th | " | " |
| December 31st | " | " |
| December 1st | " | " |

Sitting arrangements will be as already announced in previous public notices.

**K. J. HILTON**
Secretary, Minorities Commission.

# Awon Minister Fun Ile Nigeria



Awon eniti a nwo ninu aworan yi ni awon Minister to nse aseju fun apapo ile Nigeria, oruko awon ti o joko ni Olola E. M. L. Endelay Malam Ribadu Alhadji Tafawa Balewa ti o nse Prime Minister, Olola Gomina agba James Robertson, F. M. Mbadiwe ati Okotiebo. Awon ti o wa niduro ni J. M. Johnson Olola Rosiji Aja Nwachuku S. L. Akintola.

Awon nwonyi ni Aworesasa ti ase mbe lenu won nisisiyi lori apapo ile Nigeria.

Printed and Published by The Union Printing Publishing Company, 28, Kosoko Street P. O Box 467 Lagos Phone 2337